# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 872 SATURDAY JUNE 8 — JUNE 14 1963 KOBỌ MEJI (2D)

# Ogun Olomo-Komo-Omo Tun Be Sile Ni Ilu Congo

KATANGA—Ijangbọn ogun ọlọmọ ko mọ ọmọ tun bẹ silẹ ni ilu ti nwọn npe ni Katanga ni Congo ni ana larin awọn soja oba pelu awọn ọmọ-ogun baalẹ Tshombe ti o sọ wipe on ko ni jọgọ silẹ fun awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe ilẹ Congo ti nwọn ni ki on fara... ti nwọn.

Ilu kan ti nwọn nwa idarọ baaba (copper) ti nwọn npe ni Kolwezi ni ija rukurudu yi ti bẹsilẹ, awọn soja si pa ọpọlọpọ enia-dudu ati Oyinbo.

A ko ri irohin ti o daju gba lati ọdọ onirohin wa leri ija na nitori a gbọ wipe gbogbo waya erọ ti nwọn fi nsọrọ si ilu okere ni awọn ti o nja na ti ge lulẹ patapata.

A gbọ wipe Ọgbẹni Tishombe ni ti Ijọba Apapọṣe ba fẹ fi agbara gba ibiti nwọn gbe ti nwa idarọ baaba yi lọwọ on gbogbo ibẹ ni on yio pa-ṣẹ fun awọn ọmọ ogun on wipe ki nwọn fọ patapata, ki nwọn ba gbogbo nkan ti nwọn fi nwa awọn idarọ baaba yi jẹ.

Awọn oṣiṣẹ ti nwọn nwa idarọ na ni Kolwezi ni awọn yio da iṣẹ silẹ ti awọn alamojuto Ijọba Apapọṣe wọn ko ba ko gbogbo awọn soja wọn kuro lọdọ awọn ni kiakia.

## AWORAN AFOWOYA AZIKIWE GBAYI L'EKO



EKO — Nje iwọ ti o nka iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi ti lọ si Ẹhingbẹti ninu ile ti nwọn nko awọn nkan atijọ pamọ si l'Eko lati lọ wo aworan afọwọya ti Ọlọla Gomina-agba, Dokita Nnamdi Azikiwe, ti awọn alamojuto Ijọba Ilu Gesi ni ki alaworan afọwọya kan ti nwọn npe orukọ re ni EDWARD I HALLIDAY wa ya fun awọn ti nwọn fẹ fi ta ile-ẹkọ giga Nsukka lọrẹ ninu oṣu yi.

Aworan afọwọya na gbadun, gbogbo awa oniwe irohin ni a ti lọ wo aworan na ki nwọn to gbe sita ni ijẹta fun gbogbo enia lati wo. Ẹda aworan na ni o wa loke iwe yi; Ọgbẹni Ben Enwonwu, agbẹgilere ilẹ Nigeria ti o sọrọ nipa iṣẹ ọwọ Ọgbẹni Halliday fun awa oniwe irohin lọjọ ti nwọn lọ fi aworan na han. wa ni o duro ni apa osi ti aworan afọwọya na loke iwe yi, ẹnikeji ti o wa ni apa otun ni Ọlọla Viscount Head, aṣoju ijọba Gesi ni ile yi.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Odaran Kan Gba Adajo Loro Ninu Kotu

IJẸBU-ODE — Gbogbo Kotu-ganran Ijẹbu-Ode ni o pa lọlọ nigbati ọdaran kan ti awọn ọlọpa wọ wa si Kotu na bẹrẹsi gba adajọ-agba, Akin Delumọ ni ikan-ko-jọkan ọrọ ninu apoti awọn ọdaran ti o duro si lati jẹ ẹjọ re.

O... wa ti o wa ni Kotu ... ọ na ni ... o si nkan ti ... ọrọ ... na ju oruko ọdaran yi ti o njẹ Ọlarenwaju Rasaki ti akọwe kotu ... pe e lọ; were ni o ti sọ fun akọwe kotu na pe ki o gbẹnu rẹ sọhun, oruk... ti baba on sọ on kọ niyẹn.

Nwọn fi ọrọ yi lọgun, nwọn fi lọgbọn, ọdaran yi ni ki nwọn ma fun on ni 'Suna ọsan gangan, o ni on ko ni gba igbakugba.

(Wo iyoku loju ewe keji)

# Ọdaran Kan Gba Adajo Loro Ninu Kotu Ijebu-Ode

(O bere loja ewe kinni)

Ngbati Adajọ-Kotu na ri wipe ọrọ na fẹ bige badubi fun akọwẹ o., o ni ki ọdaran yi ma binu rara, ki o ja ọrọ na ye on. Ọdaran na ni ki adajọ na ma fun on ni suru agbara rara, o ni ọran ibinu ko ba on.

Adajọ na tun pe ọdaran yi lati ṣe alaye fun wipe ki o mọ ba awọn ja, ṣe orukọ ti o sọ fun awọn ọlọpa wipe on jẹ niyen orukọ korukọ ti o ba si jẹ ki nwọn kọ silẹ wipe o njẹ ki o sọ ọ, on a kọ mo eyiti awọn ọlọpa ti i pe e.

Were, ọdaran na ti beresi gba Adajọ na ni ọkan so jọkan ọrọ o ni ṣe o ri ki on mu kunmọ wọ kotu ni tabi kini o ri ti o fi sọ wipe ki on ma ba nwọn ja ni kotu. Nkan ti nṣe on kiṣe ọran ija.

Ariwo ti o npa pẹlu bi ọdaran na ti nfi ibinu sọrọ yi mu ki adajọ Delumọ paapa binu, o si sọ fu ọdaran na wipe ti ko ba jẹki onipẹsẹ ṣe on wọọ pẹlu ọrọ isọkusọ ti o nsọ on a ju u sẹwọn nisisiyi lati ọgba ẹwọn na ni yio si ti ma wa ro ẹjọ ọmọ ọlọmọ ti nwọn ni o ji gbe.

Ọdaran na ni on ko le ṣe bẹ sugbọn on fẹ ki o mọ wipe on adajọ paapa le di oku eniti nwọn yio ru lọ si itẹ oku nisisiyi.

Ọrọ yi wa jẹki adajọ na bere lọwọ agbẹjoro ọba Ọgbẹni A.D. Ajibọla bi ori ọdaran na ba fa epo. nitoripe gbogbo ọrọ ti o nsọ yi jọ ti ẹniti nwọn ni lati mu lọ yẹwo ni ọgba awọn oniwere

## Awọn Oyinbo Nfi Ise Ijoba Sile Ni Kenya

NAIROBI — Ni gẹrẹ ti nwọn ti jẹ sọ Ọgbẹni Jomo Kenyatta di Olotu Ijọba tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ dasilẹ ni Kenya ni awọn Oyinbo kan ti nwọn nṣe orişirişi iṣẹ nile iṣẹ Ijọba ilu na ti kọwe wipe awọn ko fẹ ba wọn ṣe iṣẹ Ijọba mọ.

A gbọ wipe o ti le ni adọtalerugba awọn Oyinbo ti nwọn Oyinbo ti nwọn ti ti iru iwe "emi ko ṣe iṣẹ mọ' bayi gba lọwọ wọn. A si tun gbọ wipe awọn alakoso ilu na si ti ngbaradi lati fi owo kan rẹ wọn lẹkun lori iṣẹ ti nwọn fẹ ju silẹ na.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)




Iwọ ha nwa asiki fun ra rẹ bi?

Ki yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ

latigba dẽgba nile-ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ ·mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu atipe bi o ti npẹ nibẹ si bẹni yio ma lési. Lọ bère nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

"BI IW
ASIKI

Barclays ti
idaraiya to
ninu simim
lè ri tẹlẹ, A
ọdọmọkunrin
jade lati j
Bi o ti nlọ
Ọkan ninu



fi nko èro, e
jẹ onipòwo t
ti nfi gbog
Jọdọ Barclay
pupọ. Wọn
ki o lọ si
bère ifowopa
Gbogbo awọ

pẹlu rẹ
ni abo
ri bi
apoti oniṣ
wipe nigba
na yio
bẹrẹ si f

B

Awon Iwe Asiko :

# Awon Ole Obi Pa Omo Won (2)

Ninu iwe Alufa Atilade

Ni ọsẹ ti o koja ẹnyin ọkawe wa ka bi akọbi awọn ... yi ti lọ si idalẹ kan ti ko tete pada wa sile ati bi idalẹ na ti dara fun ọmọ na ti o di olowo, ti o di ọlọ a ki o to wa pada wa sile lati ma wa iya ati baba rẹ kiri.

Iyoku itan na ni eyi, ẹ ma ka a nişo –:

## Lati Owo AKOWE

Iya ati Baba inu ile na fi tayọtayọ gba alejo na. Lẹhin igbati awọn alaru ti gbẹru kalẹ tan, awọn gba owo işẹ wọn, onikaluku si ba ọna tirẹ lọ. Ẹniti o mu alejo de ẹnu ọna ile na ti lọ. Ko si ẹlomiran mọ bi koşe ọkunrin alejo yi nikan lo ku nilẹ.

Iya inu ileyi şe akiyesi pe ẹru ọkunrin alejo yi pọ ati pe owo pupọ wa ninu ẹru na Oju rẹ mu awọnwọn si dukia alejo yi. O bẹrẹ si gbero ọna wo ni ọwọ awọn o şe tẹ gbogbo nkan ti alejo yi ru wọ ile wa yi.

Nigbati ọkunrin alejo yi, ẹniti arẹ irin ti mu sun lọ fọnfọn, Obinrin yi lọ ba ọkọ rẹ, o si sọ ohun gbogbo ti o nro ni ọkan rẹ fun u.

O sọ fun bale rẹ pe iwọ papa mọ p: talaka ni awa wa, mejeji si ndagba lai ni ohun ini kan ti a le gbẹkẹle fun akoko ogbo eyiti o sunmọ tosi. Ọlọrun si mu ifa wọle tọ wa wa. Nitorina, jẹki a pa alejo yi, ki gbogbo ohun ini rẹ ba di ti wa.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

# Eleti–Ofe D'araba

# Ibere Nla Kan Ni Eyi

Lati Owo Mopelola Amope

Ọmọ Ọba Oke Orimi, Oro le'i Ọffa

Olotu mi ọwọn, Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le ba mi tẹ Ibere kekere yi sinu iwe rẹ oloyinmọmọ ti wọn npe ni Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ yi

Ibere na lọ bayi: "N gba kan iya kan wa ti o bi awọn ọmọ meta, Orukọ Ekinni njẹ Kọla, Ekeji njẹ Kayọde, Ẹkẹta njẹ Ọmọtayọ.

Nigbati wọn dagba tan wọn sọ wipe awọn fẹ kọ işẹ ọwọ şugbọn iya wọn kọ fun wọn lati lọ kọ işẹ na, Nijalẹ ọjọ kan, awọn ọmọ mẹta wọnyi sa jade ninu ile iya wọn na. Nigba ti wọn rin titi wọn de orita kan eyiti ọna ibẹ piu si ọna mẹta.

Kọla to jẹ ẹgbọn wọn ba ọna ọkankan lọ Ẹlẹhinti nwọn ti jọ ji roro papọ. Lẹhin eyi yi, Kayọde ti o tẹle gba ọna ọtun lọ. Ọmọtayọ ti o jẹ aburo patapata gba ọna osi lọ.

Ki gbogbo wọn to pin ya, wọn sọ fun ara wọn wipe ti o ba to iwọn ọdun mẹta ki awọn tun pade ni ikorita mẹta yi.

Nigbati Ọdun meta pe, awọn mẹtẹta tun pade ni orita meta na. Lẹhin igba ti wọn pade tan, ebi bẹrẹ si pa wọn. Kọla fi ọwọ la ilẹ lẹsẹ kanna, işu si şẹ yọ ninu rẹ. Kayọde

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

## Adajo So Awon Ole Ti Won Wo Aso Olopa Sewon

ABAKALIKI — Adajọ Kotu awọn ọlọpa, Ọgbẹni Bob Nzeribe ti o ndajọ ni Kotu Abakaliki ni on fẹ ki awọn ọlọpa ti o nibẹ nilẹ yi mọ wipe on ko ni gba awọn oniwa baruku na laye ni akoko ti on ba wa lori aga idajọ.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)



Aworan ikan ninu awon omo wa ni Peter Thomas, omo odun mokandinlogun ti o joko pelu awon elere omo ilewe egbe re nigbati nwon nse ere bolu afesegba ni ilu Oyinbo. Omo Adajo Peter Thomas ti o wa ni Ipinle Iwo Orun ni omo na nse. On ni o si je enjkini ti kise Oyinbo ti nwon fi je oye Olori Awon egbe re ninu ilewe ti o nlo na

# ELETI-OFE

A NJU WỌN KO ŞE WI LẸIỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMS

K...ṣọ Street, Lagos, "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIV. No. 872 SATURDAY JUNE 8 — JUNE 14 1963

Oro Olotu

# Pope Mimo Ijo Aguda, Orun Re!

B. enikan ba wa ti o nṣe wahala lori wipe ki aiye ki o roju, ki aya gbogbo ara aiye ki o balẹ, oluwarẹ ko le se ju ti Ẹni-ọwọ POPE JOHN Ikẹtalelogun ti o jalaisi ninu Afin rẹ ni Rome ni ọjọ Aje ijẹta lọ.

Lati ọjọ ti o ti gun ori aga mimọ na ni Ẹni-ọwọ yi ti nsa agbara lọtun losi lati wipe awọn alagbara aiye fi ọwọ so ọwọ pọ ki nwọn ye mura lati ma ja ogun.

## Pope Alafia

Eyi nikan kọ ni Pope John mimọ se; o tun kesi gbogbo awọn Ijọ Ṣọṣi kakiri agbaiye wipe ọkanna ni gbogbo awọn niwaju Olodumarẹ ati wipe olowo ati talaka ni Jesu Kristi wa fun.

Iru iwa ki a ma wa alafia fun gbogbo awọn ara aiye bayi ni jẹ ki awọn ara aiye na sọ Pope John ni Pope Alafia.

Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki ẹnyin Ijọ Aguda kakiri gbogbo agbaiye pe ẹ ku ajalu, ẹ si ku aṣehinde. Jesu Kristi ki o fi ọna han yin lati le yan ẹniti yio ma ba iṣẹ alafia ti Pope John fi silẹ lọ.

# Oko Ofurufu Kan Ja Lule

ALASKA—Ọkọ ofurufu kan ti o ko ero ja lulẹ ninu okun ilu Alaska ni irọlẹ Ọjọ Aje. Gẹgẹbi irohin ti a gbọ awọn enia mọkanlelọgọrun ni nwọn wa ninu ọkọ aropileni na.

A gbọ wipe awọn jankanjankan ilu Amẹrika ni nwọn lọ ya ọkọ ofurufu na lọwọ awọn ti nwọn ni lati fi ko awọn ṣọja wọn pẹlu awọn iyawo wọn lọ si ilu kan ki o to pade agbako jija sodo yi.

Ko si ẹniti o ye ninu gbogbo awọn ero ti o wa ninu ọkọ na, Oyinbo kan ti o gbe ọkọ aropileni gba apa ibiti nwọn ti ja lulẹ na ni on ri gbogbo panti ati awọn igi ti o dabi ẹnipe nwọn ti ri s'omi ni.

# Iwe Si Olotu

ATẸGUN BURUKU

## Pa Enia Si Ni Ilu India

CHITTAGONG, BENGAL—Titi ti o fi di owu ọ ana ni awọn isọ'a ati Ọlọpa n'ọ gbe oku enia ti atẹgun buruku pa kakiri agbegbe ilu ti nwọn npe ni Bengal. O di ijẹta loni ti atẹgun a'anjanu na kọlu ilu awọn Imale India ti o se wọn lọsẹ, ti o fi di wipe nṣe ni Ijọba nda owo-inu fun awọn ti o wa laye, ki nwọn fi ri nkan fi jeun.

Gẹgẹbi irohin ti a tun ri gbọ nipa jamba atẹgun na, a gbọ wipe o ti to ẹgbẹrun (10,000) oku enia ti atẹgun na pa ti awọn ọlọpa si ri gbe lọ sin nisisiyi.

Nwọn ni awọn enia ti o si di ẹlun a inle ko niye. Nwọn ni ofo ti atẹgun na fi se awọn ju ti ọlun kẹ a ọ ni iba p p g ogbo nkan ọsin bi ẹranko ati adiẹ ni o pa tun wọn.

Mo gbọ wipe iru iṣẹlẹ na ti di emeji ti o nṣe awọn Imale ara ilu India yi lọsẹ.

## Gomina America Fake Kori

ALABAMA – Gomina kan ni ilu Alabama ni Amerika ti nwọn npe oruko rẹ George Wallace fi aake kọri wipe on ko ni ba awọn ọnọ enia dudu laye lati ma lọ kọ ẹkọ ninu ile iwe giga ti nwọn kọ fun awọn ọmọ Oyinbo Amẹrika rara.

A gbọ irohin wipe Gomina na korira awọn enia dudu tobẹgẹ ti o fi sọ wipe on ko kọ n a i ti o le ti idi ẹ jade, ṣugbọn ni ako ko ti on ba wa lori aga on ko ni gba ki awọn enia dudu ilu Amẹrika ma jọ fi aga gbaga pẹlu awọn ala ọfunfun.

A gbọ wipe Ijọba Amẹrika ti pe Gomina na lẹjọ si Kotu nla wipe ko wa sọ tenu rẹ, nkan ti o ri ti o fi sọ wipe on yio di awọn ọmọ enia dudu ti nwọn fẹ wọ ile ẹ giga lọwọ lati wọ ibẹ.

Gomina na ba awọn oniwe irohin sọrọ ni ijẹta, awọn ogun ọlọpa ni o mu iọwọ ki awọn enia dudu ma ba na a ni ana-gbe.



**Aworan yi ni ti Omobinrin kan ti nwon npe ni Judi Dench, Omo ilu Gesi ti o mo ere a npadan se pupo. Laipe yi ni o ba awon egbe elere kan ti nwon npe oruko won ni Notinham Playhouse wa si Nigeria lati wa se ere. Ere sise yi ti gbe kakiri ilu bi Amerika, Canada ati Italy.**

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

## Iwe Iyawo

Mo gbọ wipe awọn Kansilọ Eko ti mura ati ma ta? fun tọkọ taya ni iwe eri pe nwọn ti gbe wọn ni iyawo, ko ba se pe yigi ni nwon so, ko ba dana kaa ti awọn Kiriyo ma n pe ni PARLOUR MARRIAGE ni. Iyawo ni iyawo nje. K? awon obi ka ?a ti sọ wipe awọn ?i ?wo ? fi f?? ?a jọke.

M? g? ? wipe iwe-?? bayi ko ni jẹ?i awọn akokọ po ilu Eko mọ, laiya awọn aunti 'KOFORUN' papa a di?ku ni Ẹ??gbeti. Eko fẹ dara aiye fẹ bọ si ipo ti a?a.

## Iyawo Pajawiri

Nkankan ni mo fẹ bere lọwọ awọn akọwe ile minisita na, nkan na wipe awọn iyawo ti a ba gbe ni pajawiri nkọ, ṣe nwọn le fun wa ni iwe-ẹri pajawiri? Nkan ti o jẹ ki nṣe ibere ọrọ yi ni ti aiye pajawiri ti a wa lode oni. A ni OMINIRA PAJAWIRI, a ni ?ijọba Pajawiri, a ni Olotu Pajawiri, a ni A?ajọ Pajawiri, a ni Gomina Pajawiri, LỌYA Pajawiri ati Kotu Pajawiri.

Ni aiye ti a wa yi bi e?a ko ba se pele pele, ti o ba gbe ILE MOṢU obinrin ni iyawo pajawiri, oluwarẹ yio ṣe aua pajawiri, yio si bọmọ pajawiri ni kiakia.

A dupẹ lọwọ Kansilọ wa ti nwọn nfẹ bawa ṣe eto iwe-ẹri igbeyawo ?a fun wa, Ọrọ iyawo kọ jẹbẹ rara.

## Pope Mimo

Awọn Ijọ Aguda ti njẹ oye Pope o ti pẹ ṣugbọn ko si Pope ti o gba ẹye b? ti Oloye Pope J?ha ti o ṣeṣẹ jalasi ??nu ọsẹ yi. Eniọwo na jẹ ẹniti ko fẹ ki awọn oyinbo alagbara aiye pa wa tan fu? ?kan oloro b u r u k u ti nwọn ?danwo lati le sọ awọn tise lagbara to.




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last, just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

# LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, (EB). IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT. ABA.

SUB-DISTRIBUTORS:

# ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY. ONITSHA, ABA.

# Iwe Asiko

(O bere loju ewe keta)

Bi enikeni ba bere re ni aro, awa yio so fun u pe o ti ji lo ni afemoju pelu awon alaru re. Erokan so fun baba yi pe imoran yi ko dara, nitorina ko fe gba imoran na; sugbon obinrin yi bere si bu oko re pe aile pinnu lati se nkan bi okunrin ni kiakia ni ko jeki o to enia gegebi awon egbe re.

Nikehin ohun ti obinrin na bori, oko re si gba lati lowo ninu ero buburu yi. Nwon lo si ibiti okunrin alejo na gbe sun, awon si pa a sibe. Nwon sin oku okunrin na si'nu ogba won; nwon si se awon eru re lojo kakiri si'nu ile won.

Nigbati ile mo ti awon ko ri enikeni lati wa bere okunrin alejo na, nwon gba pe gbogbo nkan na ti pari; sugbon nigbati o di iyaleta ni okunri ojulumo won aujo d', o si ki won pe—'E ku amojuba, E ku ori're. Nwon bi i lere pe, 'Tani de'? o dahun pe—E ko ri alejo ti mo fi omo le wa s'odo nyin ni ale ana? Nwon ko le dahun mo, awon mejeji bere si wo ara won loju. Nigbati okonrin na bere si ma i s o nipa apejuwe ti alejo na se nipa obi re ati nipa on papa mo mo pe omo nyin ti o wa ni idale ni, nitorina ni mo se fi ranse s'odo nyin. On na a da? Ki okunrin yi to pari irohin nipa apejuwe ti okunrin alejo na se nipa awon obi re ati ti ara re awon papa ti gbo pe omo won ti nwon ti nreti lati idale ni alejo na. Ibanuje orun yi lopa iya na ati baba na, dukia ti nwon ti itori re pa omo yi si di ifa fun elomiran. Bayi ni awon obi yi fi owo ara won se'ra won.

# Ibere Nla

(O bere loju ewe keta)

ni kini on ri yi, on paapa si fi ese re na ile, ina si seyo ninu ile, won sun isu yi, won si je gbogbo won si yo, sugbon ongbe wa ngbe gbogbo won nitope ko si omi fun won lati mu. Lehin eyi ni Omotayo wa ni kini subu lu on; on nalwa fi owo gba ile, omi si seyo ninu ile na won si mu u, gbogbo won si yo bamu bamu.

Lehin eyi ni gbogbo won wa pada lo si ilu won sugbon nigbati ti won ma fi pada de ilu won na won so fun won wipe Iya won ti jalaisi.

Kola ni ki won mu on de ilu ti won sin iya awon na si. Lehin igbati won de ibe, won hu ile ibe won ba egungun oku iya won na nibe.

Kola si to gbogbo egungun yi jo, Kayode wa bo sibe o fi owo ra egungun na lese kanna egungun na si di enia, sugbon ko le mi rara.

Eleyi wa jeki Omotayo bo sibe, bi o ti gba Iya won na ni abara bayi beni iya won na ba dide ni ile o si bere si oro so. Nwon wa mu iya won na lo si ile won pada.

E jowo Olotu, mo fe mo eni ti o lagbara ju ninu awon meteta wonyi. Ekinni Nibi isu ati ati ekeji Nipa ti Iya won ti nwon ji dide.

## Adajo So Awon Ole Sewon

(O bere loju ewe keta)

Adajo yi beresi so oro yi nigbati o nse idajo fun awon olosa meje kan ti nwon beresi wo aso olopa fi ko ile onile kiri. Ewon odun merin merin ni adajc ju awon odaran na si.

Oruko awon meje je na niyi: Rufus Okafor, Nwoke Ekeozor, Kalu Eze Robison Nkedirim, Victor Okpelue (Paripasu okunrin Hilary Onyegbenam ati Peter Anoka.

Awon olopa ni wahala awon olosa yi ti su awon, nwon ni lojojumo ni uwon awon ara ilu lenu ti nwou nse won lose pelu ada ati ibon.

Oga awon olopa ni eyi ri nwon se ti o bu won owo lowo yi tile utu ju.



## Oba Elizabeth Ni Australia

**Aworan ti e nwo yi ni ti Olola Oba ilu Oyinbo Elizabeth Keji nigbati o nsi ile alaisan awon omokekere ni ilu kan ti nwon npe ni Melbourne ni Australia laipe yi.**

## British Voluntary Contribution:

# £3½-Million To Freedom-From-Hunger Campaign

LONDON—Earl De La Warr, chairman of the British branch of the Freedom-From-Hunger campaign, stated in a letter to the London "Daily Telegraph" yesterday that the British Committee has been able to commit themselves to over £3,500,000-worth of carefully considered and, definite projects in 44 countries.

Thanks was due to the response of "thousands' if not million of ordinary people in Britain", said Earl De La Warr.

He added: "We should at least be able to double what has already been done if the response to the work of our 70 affiliated voluntary societies and 960 local committees continues on anything like the scale of the past few months."

## British Table Tennis Star Britain

LONDON—Chester Barnes, 16-year-old star of British table tennis, will leave London for a month's exhibition tour of Nigeria immediately after competing in the European junior table tennis meeting at Duisburg, Western Germany, which ends on 11th July.

According to Mr. Jack Farnsworth, Treasurer of the Nigerian Table Tennis Association who has been helping to arrange Barnes tour in Britain with his manager-coach, Mr. Alec Brook, the young English player will give exhibition matches in Lagos, Ibadan, Kaduna and possibly Kano. In all these centres he will play against Zoltan Berczik, the Hungarian table tennis stars who has already arrived in Nigeria.

"I am hoping that Barnes will be able to coach a couple of dozen of our Nigeria players in every centre he visits," Mr. Farnsworth told our correspondent yesterday. "These visits by leading players from Europe give a tremendous fillip to the game in Nigeria. We have a great potential and table tennis could well become almost a national game as it has in Japan."

## Nigerian Stamps To Feature U. S. Space Achievement

LAGOS—Nigeria will issue special postage stamps this month featuring the American space programme.

The space issue will consist of two values: A six pence issue honoring Major L. Gordon Cooper's historic 22-orbit space flight and a shilling, three pence issue featuring the U.S. Navy research ship 'Kingsport,' which was anchored in Lagos Harbor, to track the Syncom satellite.

Nigerian Government participated in both space feats. The Kano Tracking Station in Nigeria was operating during the Cooper flight; and the Nigerian Government contributed the base and Nigerian scientists for the Syncom Space Project.

# Hon Akinfosile Opens Ikorodu Exchange Telephone

IKORODU — The Minister of Communications, Chief the Hon. Olu Akinfosile, this week officially opened the Ikorodu Telephone Exchange. The new exchange, was erected at a cost of £51,000.

Speaking at a short ceremony to mark the opening, Chief Akinfosile called on the people of Ikorodu to make the full use of the exchange. He added that it was when they did so that the Federal Government would be encouraged to get on with the programme of expansion in the area. Later, the Minister declared the open by making a telephone call to the Governor of the West, His Excellency, Sir Joseph Odeleye Fadahunsi, the Deputy Premier, the Hon. R. A. Fani-Kayode, and the Olubadan of Ibadan, Oba I.B. Akinyele all of whom also chatted with the Federal Minister of Information, the Hon. T.O.S Benson the Anyangburin of Ikorodu, Oba S.O Ladega the Hon S O Gbadamosi and Hon Adeniran Ogunsanya M.P.

Both Chief Akinfosile Oba S O Ladega were conducted round the exchange by the Senior Telecommunications Engineer, Mr I O Lediju

## Britain Buys More Goods From Nigeria

LONDON—Nigeria had a good month's trade with Britain in April, according to figures just published by the Board of Trade in London.

Nigerian produce sold to Britain accounted for £8,694,279, compared with £6,518,241 in April last year.

The value of British coffee, cocoa, tea and spices purchases from Nigeria rose steeply from £67,037 in April last year to £2,275,000 this April.

Under the heading "textile fibres and their waste" the value of British imports from Nigeria have double from £239,65 in April last year to £512,413 this April.

BA NWA
UNRA RE"





BARCLAYS
BANK
D.C.O.

## Awon Aguda Sinku Pope Ni Rome

ROME—Gbogbo awon alufa jankanjankan ti Ṣọṣi ijo awọ Aguda kakiri agbaye ni nwọn pesẹ ṣoṣọ si ibi ẹsin isinku Ẹni-ọwọ Pope John Kẹtalelogun ti o jalaisi ni ọjọ Monday ti o kọja ni afin ti o ngbe ni Rome.

Ẹni ọdun mọkanlelọgọrin ni ẹni ọwọ Pope yi o si se olori ijọ gbogbo awọ elesin Aguda fun ọdun mẹrin ati oṣu meje. O ṣe gudugudu meje nipa ikilọ ti o nse fun awọn alagbara aiye wipe ki nwọn ye rọ nkan ija fun iparun awọn ọmọ araiye.

Ni irọle ijẹta ni nwọn sinku rẹ pelu agbelebu kan ti o fi igba kan ra lọwọ tálaka agbẹ kan.

### Pope Tuntun

Ni Eko, awọn Ijọ Aguda ṣe isin isiku pataki kan ninu Ṣọṣi wọn ni Popo-Aguda ni irọlẹ ijẹta fun Ologbe Pope na. Isin na kamama. Olori awọn Alufa Padi Ọgbẹni J K Aggey ni o se iwasu nibi isin na; o sọ bi Ologbe Pope Johno ti jẹ olufọkansin to ki o to jalaisi.

Ni Wednesday ọjọ mọkanla loni ni awọn agbalagba alufa Padi yio ṣe ipade kan lati yan Pope mirau. Ọlọrun ki o fi ọna han wọn, ki nwọn le yan eyiti yio ṣe aiye ire fun gbogbo wa.

# Ọlọla Nnamdi Azikiwe

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Aworan na gbadun, o si gbamuṣe ọjọ mẹjọ ni nwọn fi silẹ nisisiyi wipe ki gbogbo awọn enia ma wa wo o l'Eko, o di ọjọ Jimọ ti o mbọ yi ki nwọn to gbe e kuro ninu ile, ti nwọn sọ wipe ki a ma wa wo aworan Ọlọla Azikiwe wa na.

Ogbẹni Halliday ti o fi owọ ya aworan na jẹ baba ẹgbẹ fun gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ afọwọyaworan ni ilu Gẹsi. On ni o ma nfowo ya aworan awọn enia jankan jankau bi ọba awọn ọmọ ọba, awọn ọlọla ati ijoye ni ilu Oyinbo.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ nipa Ọgbẹni Halliday na, akọkọ ti yio kọ fi ọwọ rẹ ya aworan enia-dudu niyi, ko si wa si Nigeria ri, aworan ti Ọlọla Azikiwe yi na ni o gbe wa si Eko, o si dabira si ara nkan ti o ya na.

Irohin ko to afojuba ni aworan na, o si ga to ẹsẹ bata mẹrin lati ilẹ.

## Awon Oyinbo Nfi Ise Ijoba Sile Ni Kenya

(O bẹrẹ lati oju ewe Keji)

Gẹgẹbi iwe-ikede Ijọba ti nwọn ti o jade laipẹ yi ni awọn Oyinbo, nwọn ni owo ti awọn onilekun ti nwọn yio san fun ẹnikọkan ko gbọdọ ju ẹgbafa pọnun £12,000) lọ. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ fisẹ silẹ ni lati sọ fun awọn tele; awọn fẹ iwe asotẹlẹ oloṣu mẹfa lati ọdọ oluwarẹ.

# Omobinrin Jalaisi Lenu Ise

SAPẸLẸ— Ariwo ta gboo ni ile awọn alaisan Sapẹlẹ ni ijẹta nigbati obinrin ọmọge kan ti o nṣe iṣẹ ẹrọ-gbohun-gbohun (telephone attendant) ti nwọn npe orukọ rẹ ni Veronica Okpara ṣubu lulẹ ti o daku bamubamu lẹnu iṣẹ rẹ.

Gbogbo awọn dokita ati awọn alabaṣiṣẹ ni nwọn du ọmọge na nibiti o gbe ṣubu si wipe ki o ma le ku, sibẹsibẹ Veronica lọ si ọrun alakeji.

Nigbati nwọn sọ fun iya rẹ, o ni nkankan ko ṣe ọmọ on ko to kuro nile, kinni on kan yi.


GREAT NIGERIA INSURANCE CO. LTD.

(INCORPORATED IN NIGERIA)

FOR ALL CLASSES OF INSURANCE AT COMPETITIVE RATES

LIFE

ENDOWMENT, CHILDREN'S EDUCATION PENSION SCHEMES.

FIRE

LOSS OF PROFITS, PERSONAL ACCIDENT, PUBLIC LIABILITY ETC.

Head Office:

39/41 MARTINS STREET,

P.O. BOX 2314 LAGOS

Telephone 25251

Branches:

ABEOKUTA, AGEGE, AKURE, ASABA, BENIN-CITY, IBADAN, IJEBU-ODE, ILESHA, OSHOGBO, SAPELE & WARRI.



## Akiyesi

E ma polowo Oja yin sinu iwe irohin ELETI-OFE losose.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370; Editor, (Olotu) Ola, Onatade, 15, KosọkọStreet, Box 467, Lagos.